# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV 853 LAGOS SATURDAY JANUARY 19 — JANUARY 25 1 3 KOBO MEJI (2D)


# Tani O Pa Ologbe Olympio? Ota Ile Ni Tabi Ota Ode!! KINI FA SABABI!!!

LOME—Bi o ko ba lọ ki o yago fun mi lọna ni ọrọ loru ọganjọ lọjọ Aiku (Sunday) nigbati awọn jagunjagun Ijọba ilu Togo wọle lọ ba alakoso Ijọba wọn ti nwọn npe ni Saylvanus Olympio pẹlu ibọn lọwọ wọn ti awọn ni awọn fẹ ki o fi akoso ijọba na le awọn lọwọ lọgan.

Onirohin wa ni loju orun ni alakoso na wa ninu ile rẹ ti nwọn fi ji on na pẹlu iyawo rẹ ati awọn ara ile rẹ pe ki o ṣe iwe fun awọn pe akoso Ijọba ilu Togo ti kuro lọwọ on. Ọrọ na ba Alakoso na lẹru, o si ni ki nwọn duro de on, ki on mu nkan ti on yio fi ṣ'ewe fun wọn ninu iyara.

Bi alakoso ti wọ iyara tan, ẹwu ati ṣ.koto rẹ ni o mu ti o gba ọna ẹhinkule jade, ko mọ wipe gbogbo ile on ni nwọn ti fi awọn ṣọja yika.

Bi o ti nsalọ ti o ni ki on wọ ile awọn ṣọja Ijọba ilu Amerika, oporo ahaya ọta ibọn ni nwọn da bo, o ṣubu lulẹ, o si ku bamn-bamu.

## Kilo Fa?

Nkan ti o fa sababi a nfi agbara gba Ijọba yi ni ọpọlọpọ awọn ara ilu Togo ni ko ye awọn rara nitoripe awọn ko fi igba kan ni ikunnu si alakoso Ijọba ilẹ na. Ṣugbọn awọn ṣoja ti nwọn lọ kaa mọ'le ni owoiṣẹ ti nwọn nsan fun awọn ko tẹ awọn lọrun rara Nwọn ni eleyi ni o fa sababi ọrọ na.

## Tabi Ghana?

Ṣugbọn gbogbo awọn alakoso Ijọba okere ni awọn ni ifura si alakoso Ijọba ilu Aganyin (Ghana) pe ko ni ṣe alaimọ nipa ọtẹ ti awọn ṣọja na di si Ologbe Olympio nitoripe lati ọjọ diẹ sẹhin ni ede aiyede ti wa larin awọn Ijọba ilu mejeji

Dokita Kwame Nkrumah tiṣe alakoso iln Ghana fi ẹjọ Ijọba Togo sun ara wọn wipe awọn ni o mgbe awọn ara ilu on ti o nditẹ lati pa on pọn sẹhin, gbogbo awọn ọlọtẹ na ni nwọn si wa ibi kan fori pamọ si ninu ilu awọn ara Togo na ti nwọn ntibẹ wa ipalara fun on.

Olofintoto "Eleti-Ọfẹ" ni awọn isansa ara ilu Ghana ti o nsa kuro nilu na lọ si ilu Togo fun abo le ni ẹgbata (6,000) enia, gbogbo wọn si ti kun fun ibẹru nisisiyi nitoripe alakoso ti o ṣẹṣẹ bọ sori aga ti nwọn npe orukọ rẹ ni Nicholas Grunitzky, ni ti awọn ara ilu Ghana ni on yio ṣe nitoripe on ko fẹ ija rara lati ọdọ awọn alakoso ilẹ na.

A gbọ irohin wipe ọpọlọpọ awọn enia na ni nwọn ti nwo ilẹ Nigeria bi ibi isadi tuntun ti awọn le salọ fun abo nitoripe ilu wọn ngbona fun wọn.

## Kayode Kilo Fun Oba Odemo

Shagamu—Ọgbẹni R. A. Fani-Kayode tiṣe igba-keji Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ṣe ikilọ pataki kan fun Ọba Samuel Akinsaya, Ọdẹmọ Ishara wipe awọn gbọ wipe nwọn ṣe ipade Igbimọ ibilẹ kan ni ọsẹ ti o kọja nwọn si ṣe ipinnu wipe awọn obinrin ni lati ma san ponun kọkan owo ori.

Ọgbẹni Fani-Kayọde ni Ijọba awọn ko ran wọn niṣẹ yi rara, awọn ko fẹ di ajaga owo-ori ru awọn obinrin nibi kan rara; ọna ki nwọn le bu ẹtẹ lu Ijọba awọn ni nwọn nwa kiri.

O ni awọn si ti duro fun ẹnikẹni, ko ba ṣe ijoye abi awọn lọba-lọba ni ti nwọn ba mura tan lati ba eto Ijọba na jẹ mọ awọn lọwọ, lati fi idan han an.

## Won Fi Ada Ge Akowe Kotu Lapa

AFIKPO-Akọwe kotu kan ti orukọ rẹ njẹ James Nwankwo pade agbako lọjọ ti o lọ fuu ọkunrin Ibo kan ni iwe ipẹjọ ni ileto kan ti nwọn npe ni Omuobo leti Afikpo la.pe yi.

Onirohin wa ni bi James ti de ọdọ ọkunrin na ti o sọ fun un wipe on mu iwe ipẹjọ wa fun ni ọkunrin ọdaran na ni ki o kuro ni iwaju on ti ko ba fẹ ri Eṣu. Akọwe kotu na ṣebi awada ni o mba on ṣe.

Lọgan o ti sare wọle o mu igudan, o si ge e ni apa silẹ, o ni ẹnikẹni ti o ba sun mọ ọkunrin akọwe kotu na nibiti o gbe njẹ aporo ibọn ni on yio yin fun oluwarẹ pẹlu akọwe na.

Awọn ara abule na ni lati sare lọ pe awọn ọlọpa wa lati Afikpo ni ki nwọn to le gbe akọwe-kotu na lọ si ile iwosan, ṣugbọn ọkunrin ti o ṣa lada ti fi igbo bora nigbati o ri awọn ọlọpa lojiji.

## Awọn Ọlọpa Ko Awọn Ti O Sẹ Iwe Aiyederu

ONITSHA—Ogunalọgọ awọn Ọlọpa'nu ni awọn Ijọba fi ranṣẹ si Onisha lati wa ko awọn kan ti nwọn ntẹ iwe-aṣẹ mọto (driving licences) alaiyederu kakiri. Oju iriuwo iwe aiyederu na lọ ti ọwọ awọn ọlọpa tẹ.

Awọn ọlọpa si ti ko awọn kan ti nwọn mba ro ẹjọ lori iwe aiyederu na, awọn na ni Joseph Igbokwe, Sunday Okafor, Cletus Okonkwo, Chukwujekwu Okoli, Emmanuel Obiesie ati Godwin Uche, lọ siwaju adajọ Kotu Onisowo ni gbogbo wọn.

Awọn ọlọpa ni ki adajọ sun ọjọ lati gbọ ẹjọ na siwaju nitoripe awọn ti awọn tun fẹ ko lori ọrọ na pọ.

Awọn Ọlọpa tun ṣe alaye wipe awọn ti tun ri awọn ẹlomian ko ni ilu Owerri lori ọrọ iwe-aṣẹ mọto alaiyederu.

---

## Ọmọlewe Kan Pa Enia

ABẸOKUTA—Awọn ọlọpa mba ọmọ kekere kan ti orukọ rẹ nje Fatai Ayinde ọmọ ọdun mẹrindinlogun ro ẹjọ apania ni Kotu nla, nwọn ni o fi ọbẹ pa Tobi Oyelana.

Ẹnikẹni ninu awọn ẹleri ti o nje Akintoye Akinyẹmi, ọmọ ilewe giga ti nwọn ni Abẹokuta Grammar School ni oju on ni ọrọ na ṣe ṣẹlẹ ni ita Ogbon: ni Itẹsi lọdun ti o koja O ni lẹrun ni ọdaran na fi ọbẹ gee ti ẹjẹ si bẹrẹsi tu jade Ẹlẹri yi ni ki on to mu iya on dd ibẹ, ọmọ na ti ku.

Ẹleri miran Kashimawo Bashọrun, ni on ri ọdaran na ti o l Tobi lẹwu mu papankoko bi on si ti ni ki on la wọn ni ọdaran na fi ọbẹ ge ọọ ni ọmọ'ka, lẹhin eyi ni o ba tun gun ẹniti o mba ja' lọbẹ ni gbogbo agbo ba tuka.


# The advanced quality of the Fiat "sixes"

## FIAT 2300 and FIAT 1800 B

more power, elegance, comfort, disc brakes



The Fiat 2300

PRICES

| | | 2300 Ex Lagos | 2300 Ex Turin | 1800 B Ex Lagos | 1800 B Ex Turin |
|---|---|---|---|---|---|
| STANDARD | SALOON | £1,380 | £698 | £1,250 | £638 |
| STATION | WAGON | £1,530 | £775 | £1,380 | £710 |
| SPECIAL | SEDAN | £1,780 | £845 | | |

ALWAYS REMEMBER:
FIAT CARS PURCHASED AFTER 1st JANUARY, 1963 ARE COVERED BY THE LONGEST GUARANTEE:
12 MONTHS OR 12,000 MILES

## LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (EB), IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT HARCOURT, ABA

O to iwọn oṣu melo kan sẹhin igbayi ti opitan wa, wa, "ỌMỌ ABATI" ni Ago Owu l'Abẹokuta kọ itan ti a ṣe ẹda rẹ yi; nigbana Ọba Alaiyeluwa Ademọla keji wa laiye ṣugbọn lẹhinna awọn awọn nkan mẹta pataki miran ti ṣẹlẹ ni ilu Abẹokuta ti o yẹ ka ri tọka si fun ẹnyin ọkawe wa. Ekinni ni ti ọmọ Ọba na, Adenrele iyawo Oloye Odutọla ti o sọnu, ti nwọn wa titi di ọjọ oni, nitoripe ni OJOKORO leti Agege ni nwọn bi i si, o si ni itumọ ti a fi sọ arabinrin na ni ADENRELE Ekeji ni ti ọmọ ọmọ Ajabọ, Oloye Adekunle Coker ti nwọn fi ṣe ọkan ninu awọn Adele-ọba si Ake. Ẹkẹta ni ti awọn Ologboni Abẹokuta ti ỌMỌ ABATI ni awọn ni ida oṣelu wa lọwọ rẹ ni ilu Ẹgba. Ẹnyin na si ri i wipe bẹni itan awọn Ologboni na ri lati igbati ọba yi ti waja.

Olotu

# Itan Oba Alake Ademola Keji

## Egba Soro Sin

Gbogbo ọmọ Ẹgba ọmọ Lisabi ni oko ati ile ni o mọ wipe awa Ẹgba a ṣoro sin ; Ọba wa ti a nsọ itan igbesi aiye rẹ si nma nsọ bẹ nigba gbogbo ti o ba nsọrọ ni awujọ awọn baba wa oṣelu, awọn Ologboni nitoripe awọn Ologboni ni oṣelu ni ilu Abẹokuta ni aiye atijọ ki aiyena to di ti awọn ọdọmọde ilu lọkunrin ati lobinrin nisisiyi.

Tani ko mọ wipe ọrọ di Ẹgba ṣoro sin nigbati ede aiyede de sarin Obawa pẹlu alamojuto Ijọba Ẹgba ti atijọ ni iwọn nkan bi adọta ọdun sẹhin ti Ọba wa na binu fi iṣẹ Aṣoju Ẹgba l'Eko silẹ ti o bẹrẹsi ṣe iṣẹ agbẹ ni Ojokoro leti Agege.

## Ajobo

Ọba wa yi nikan kọ ni ọmọ Ẹgba pataki ti o fi iṣẹ agbẹ ṣe iṣẹ nigbati a nsọ itan rẹ yi: awọn bi Ologbe Pa Jibowu baba Ologbe Olumuyiwa Jibowu Adajọni Ẹgba Kotu ganran; Pa J. K. Coker ọmọ AJOBỌ, ẹniti o ṣe ọna ti Ọba wa yi ti ṣe de ori oye baba rẹ. Ẹ o ma gbọ eyi ni ẹkunrẹrẹ ninu itan mi nigbamiran.

Nigbana ina koko (cocoa) bẹrẹsi tan ni ilẹ wa ni alaiyeluwa Ọba Ademọla Keji si wa ninu awọn ọmọ Ẹgba ti o gbin koko (cocoa) jaburata gbogbo nkan si nlọ deede fun un.

Ni Ojokoro yi ni o gbe wa ti o bi Adefẹgbe aya Oloye Sholankẹ ti l'on pẹlu ọkọ rẹ wa l'Abẹokuta; ibẹ na ni o ti bi Aderẹmilẹkun aya Ọmọ'ba Adeleke Adedoyin ("Seriki Tulasi") ti on pẹlu ọkọ rẹ wa ni Ibadan nisisiyi ati Adenrele iya abiye (Nurse) ni ile awọn Alabiyamọ ni Ijẹmọ ni Abẹokuta lọwọlọwọ nisisiyi.



Ologbe ALAKE ABẸOKUTA

ṢUGBỌN A FẸ KI ẸYIN TI ONKA ITAN IGBESI aiye Ọba Alake ṣe akiyesi wipe lẹhinti opitan wa, ỌMỌ ABATI ti kọ itan yi tan ni Ọmọ Ọba Alake ti a npe ni Ademọla "iya Abiye" na sọnu, ti o di ẹniti nwọn nwa kiri ilu Abẹokuta ati igbo Dahomey titi de ilu Ghana; nwọn koi ti ri ọmọ Ọba na titi di ọjọ oni. Ẹgbọn awọn ọmọ-Ọba ti a darukọ yi ti o si jẹ BẸRẸ fun gbogbo awọn ọmọ ọba yoku ni Ologbe ọmọ-ọba Adedoyin aya Kamson.

## Ogun Ijemo

Nigbati Ogun Ijẹmọ yio fi bẹ sile ni ọdun mejidinladọta (1914) Ladapọ Alake isisiyi, ti kuro ninu awọn ti o mba Ọba Gbadebọ Alake igbana da imọran nipa ọrọ ilu. Awọn Yoruba ni alairiọ gun, alaimọọ tẹ ni jẹ ki iyan ni koko. Iru ọrọ bayi ni o fa ti baba arugbo ti o ku si ọwọ awọn ọlọpa Ẹgba nibiti nwọn gbe da duro si lori ọrọ a nmu ni ṣe iṣẹ nipa.

Nigbana awọn lebira oniṣẹ ọba ko wọpọ, nitorina awọn ọlọpa nlo aṣẹ wọn lati mu ẹnikẹni ṣe iṣẹ, bi a ge koriko kuro loju ọna tabi ki agba ile ilẹ-ọba tabi ọgba awọn Ọlọpa, nipa iru iwa bayi jẹki ọpọlọpọ awọn ara ilu nigbana ni ikunsinu si Ọba Gbadebọ ati awọn alabaro rẹ. Alafia ko si si ni ilu mọ, gbogbo rẹ wa di rukurudu.

Ọmọ Ẹgba ti o ba dagba diẹ nigbati nwọn ja Ogun Ijẹmọ a ma fi inu ṣepe fun awọn ti nwọn jẹki nwọn "rẹ awọn ara Ijẹmọ bi eni rẹ'la. Ọtẹ Ijemọ yi ko ba ti pọ tobẹ bi ko ba jẹ ti ẹtan ti nwọn fi tan awọn ara Ijemọ lọ si ojude Ọba Gbadebọ Alake ni August 1914 wipe awọn fẹ pari ija edeayede na fun wọn nibẹ.

Ogun Jamani (German) ti akoko ṣẹṣẹ bẹrẹ ko ju bi ọjọ mẹrun lo, gbogbo ṣọja ti nwọn ti nko lọ si Kameru (Cameroon) ni nwọn dapada nigbati Ọba Gbadebọ kesi Ijọba Gẹsi wipe ki nwọn ran on lọwọ. Gbogbo oju awọn ṣọja na lo nwo Hanun—Hanun.

Oyinbo Ọga awọn ṣọja ti o ba wọn wa pa apa ko ni suru. Ni oke Aro ni o gunlẹ si ti o fi ẹro-jigi wo gbagbo ilu Abẹokuta ti o ni ki on rọ agba-ibọn si ki on tete ṣe awọn ara Abẹokuta lọṣẹ, ki on le tete pado si oju ogun Jaman (German) ni Kamẹru nitoripe iyẹn ni o jẹ pataki ni oju on alara. Ọpẹlọpẹ Oyinbo Kọmisanna Gẹsi ti o wa ni Oke Igbeni ni Ibara lọjọna, ti o ba wa bẹẹ wipe ki o wọ ilu. Sibẹsibẹ nibiti nwọn gbe so wipe awọn fẹ pari ija fun wọn.

Woyoku loju ewe kẹfa

# ELETI—OFE

ANJUWỌN KO SE WI LEJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28 Kosoko Street, Lagos. "ELETI—OFẸ" LAGOS
P. O. Box 468 Phone 28370

VOL XIV. No. 854 SATURDAY JAN: 19, - JAN. 25 1962


# Kilo Fa?

Awa oniwe irohin "Eleti-Ọfẹ" ba awọn aladugbo wa, ara ilu Togo kedun iku oṣelu balẹ wọn ti orukọ rẹ nje Sylvvanus Olympio, ti awọn ọlọtẹ lu pa ni owurọ ọjọ Aiku (ọjọ Ọsẹ,) ti nwọn si fi agbara gba Ijọba ilu Togo na lọwọ rẹ.

Gẹgẹbi itan ti a gbọ nipa oṣelu balẹ na, a gbọ wipe oṣe ọmọluwabi pupọ ati pe olotitọ ati olododo ni, ṣugbọn ko si ẹniti o le tẹ araiye lọrun ni ọrọ rẹ na.

Kilo fa? A gbọ wipe awọn kan ninu awọn ara ilu rẹ ni EBI lo faa. Ebi, ọ-gaja fọwọ mẹkẹ. Ebi ki wọ inu ki ọran miran wọọ.

Ju gbogbo rẹ lọ, iku Ọgbẹni Olympio kọ gbogbo wa lẹkọ wipe ki a maṣe kọ ohun awọn ara ilu, nkan ti nwọn ba nfe ni ki a ma ba wọn fẹ ki alafia le ba wa kalẹ.

# Adupe Pupo

Irohin pataki ti a gbọ lati ọdọ onirohin wa ni Ibadan nipa ọrọ ti Oloye S.L. Akintọla, Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ba awọn oniwe irohin sọ fi wa lọ-kan ba lẹ, wipe ire mbọ wa fun gbogbo awọn e n i a Ipinlẹ Iwọ Orun na.

A gbọ wipe Oloye Akintọla ni gbogbo ẹru "du-kia" ti awọn oniṣowo ti nwọn npe ni National Invest-ment and Properties Company Limited fi owo olowo ko jọ ni awọn yo gba lọwọ wọn lai ku epinni.

Ki a mọ p'arọ ko si ẹniti ko mọ wipe alufa nsanra ijọ nru ni nwọn da ẹgbẹ oniṣowo na silẹ nipa owo awọn agbẹ tiwọn lu ni po'npo lori iṣẹ owo na.

Oloye Akintọla, a dupẹ lọwọ yin ati awọn ọmọ-lẹhin yin; ẹ ba wa tun Ipinlẹ Iwọ Orun ṣe o.

# Iwe Si Olotu

## E Ko Iwe

Ẹ jọwọ ẹ ba wa kesi wọn olotu ile posu ọfisi ki nwọn jọwọ, ki nwọn tete ma ko iwe ti a nda si inu apoti pupa ti nwọn ri mọlẹ lode (Pillar Box) kakiri ilu Eko ati agbegbe rẹ nitori pe ọpọlọpọ igba ni a n g b ọ wipe nwọn ko tete ko awọn iwe ti nwọn ju sinu nwọn.

Emi ni,
Eko Ajala


# NIGERIAN PORTS AUTHORITY

## TENDERS FORUPPLY OF LORRY TRANSPORT

Tenders are invited from lorry transport contractors normally operating in Port Harcourt for carrying out the following works for the period of one year:-

(a) conveying produce on a tonnage basis by suitable flat lorries from Arcon Sheds and Warehouses in Port Harcourt Quay to ships' side within the area of the Q"ay or from ships' side to the Arcon Sheds and Warehouses within the same area;

(b) the supply of suitable vehicles up to and including 10 tons capacity on a time basis for work either within or outside the quay area other than for the purpose covered in (a) above.

2. Requisitions for lorries will depend on the needs of the Dock Superintendent which will fluctuate considerably from day-to-day but contractors must be able to meet requirements at all times.

3. No labour will be required of the contractor to load or off-load produce and this fact must be borne in mind when quoting rates.

4. Contractors interested should apply to the undersigned or to the Port Manager, Nigerian Ports Authority, Port Harcourt, for the Form of Tender including the draft of the Agreement which will be entered into.

5. A deposit of £10 is required to be made by each contractor wishing to tender before the Form of Tender can be issued. Such deposit should be made to the Authority's Cashier either at Apapa Quays, Lagos, or at Port Harcourt Quay, Port Harcourt and the receipt presented to either the undersigned or to the Port Manager, Port Harcourt, to enable the Form of Tender to be issued. Deposits are returnable only on receipt of a bona fide tender.

6. All tenders, irrespective of where the form has been obtained must be enclosed in sealed envelopes, marked "CONFIDENTIAL-TENDER FOR LORRY TRANSPORT, PORT HARCOURT" and must be submitted to the Secretary to the Authority, 216, Broad Street, Lagos, to reach him not later than 4 p.m. on 31st day of January 1963.

7. The Authority does not bind itself to accept the lowest or any tender.

BAYO KEHINDE
Secretary to the Authority.

N.P.A. Notice No. 850.
8th January, 1963.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## Ajobo

Ninu iwe mi ti mo kọ ni ọsẹ ti o kọj lati fi da yin lara ya, mo sọ irohin fun yin bi awọn ọmọ ọba l'Ake ti bẹrẹsi du oye lati jẹ ọba Alake, eyi ko dun mi rara nitoripe bi ko ba ṣe wipe emi alara paapa jẹ ọmọ ọba obinrin ni, emi na ni lati fi iwe sọwọ si awọn ti o nfọba jẹ wipe Oye-kan mi.

### Coker

O jẹ aṣa awọn Ẹgba ti ọba Alake kan ba ti waja, awọn ni lati yan "Adele" kan si Afin ni Ake l'Abẹokuta. Nigbati ọba Gbadebọ waja ni May 28, 1920, ọdun mejilelogoji, Pa J. K. Coker "ỌMỌ AJỌBỌ" ni nwọn fi ṣe BABA MSINKU, nigbati ọba Alake Okunkẹnu (baba Gbadebọ) waja ni 1862, ẹgbọn Pa Coker ti o njẹ Ṣomoye, Basọrun Ẹgba ni o ṣe baba msinku ọba na. Lọjọ oni Oloye Adekunle Coker, Oluwo Iporo jẹ ọkan ninu awọn meji ti awọn Ẹgba ni ki nwọn ma ṣe "Adele" fun ọba Ademọla, ọmọ Pa J. K. Coker, Ajọbọ ni oloye Adekunle. Ara Iporo, ọmọ Olowu, ki o ba rai ki aburo rẹ, Olubọ, Bọlade ati aburo rẹ Alufa ijọ Afirika. Ẹ ku atijọ, Ẹ-ku-atijọ mọ ara wọn ri.

### Ni Iporo

Awọn agbalagba ni ọmọde ko gbọdọ ṣibẹ ni ọrọ ti o de le nisisiyi nipa ẹgbẹ awọn ọmọ ọba Alake ti nwọn so panpa lori awọn BABA wa, OLOGBONI afọbajẹ, wipe a fi ẹnu awọn ba fi iwe rẹ sọwọ si wọn ni nwọn ni lati gba iwe rẹ yẹwo. Emi Ayiluka gbọ wipe awọn ọmọ ọba ti o fi iwe ranṣẹ wipe Oye kan awọn ti di ẹni mejila nisisiyi, awọn miran ti o wa ni oke Oku paapa ti fi iwe ti wọn ranṣẹ, ko ti tẹ awọn Ologboni afọba jẹ lọwọ ni.

### Oyekan Mi

Emi alara paapa sare pajawiri lọ si Abẹokuta ni ... lati mọ bi ọkan ti ... si ni ilu Ẹgba; ọkọ a-ko-yoyọ (yanrin) ti mo wọ ni ko jẹ ki mba ipade ti awọn baba wa OLOGBONI AFỌBAJẸ se, ṣugbọn mo ri awọn "Adele-Ọba" Alake mejeji ni Afin.

Mo gbọ wipe ninu awọn ọmọ ọba ti o fi iwe-ẹbẹ ranṣẹ wipe OYEKAN awọn ni Lemọmu Iporo, Alufa Bamgbola (iran Ọba Okikalu) ati ẹgbọn mi, Oloye Ladipọ Shomoye ("Dansaki"); boya ẹnyin ewe igbayi le mọ mọ "Dansaki" mọ, ọmọ ọba ni lọtun losi l'Owu ati l'Ake. Ṣugbọn ko tilẹ yẹ ki a gbagbe awọn TAYLOR ni AGỌ ỌBA. Ọmọ ọba ni wọn; boya ẹ le sọ wipe bawo ni ti nwọn ti jẹ; awọn ọmọ Ẹgba loko ati lodo mọ Ologbe Adajọ Taylor wipe on na jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ọba ti o nfọbajẹ. Adajọ Taylor, ọrun re!

# Ile'we Giga Se Ajo-yo Odun Jubili Won

IJEBU-ODE — Ni gbogbo ọsẹ ti o kọja ni awọn ọmọ ilu Ijẹbu lọkunrin ati lobinrin ṣe ajọyọ ... ọdun ti nwọn ti da ile-iwe giga ti nwọn npe ni Ijẹbu-Ode Grammar School silẹ; gbogbo ẹsẹ awọn agbalagba ti o ti lọ ile-iwe ninu ile iwe na ni o ... sibe siba-siba.

Ọgbẹni N.E. Osisanya tiṣe tiṣa agba ile'we na nisisiyi sọ ọrọ pupọ ninu ajọyọ na, o ni inu on dun lati ri wipe ninu asiko ti on se alakoso ilewe yi ni AJỌYỌ ODUN JUBILU ti nwọn da ile-iwe na de, o ni ṣugbọn ju gbogbo rẹ lọ, on bẹ awọn ọmọ Ijẹbu loko, ni'le ati lẹhin odi, ki nwọn na ṣe ... awọn ... adura.

Onirohin wa ti ... fun wa wipe ajọyọ odun Jubili na ka ... ni Ijẹbu-Ode nitoripe gbogbo awọn obi lọkunrin ati lobinrin lo peṣẹ sibẹ.

Ẹ o ma gbọ irohin yoku lodo "Ayiluka" wa ti o lọ si Ijẹbu-Ode fun ajọyọ odun Jubili na.

Advert. NO. 8.

## Federation Of Nigeria Fourth Development Loan

The Central Bank of Nigeria has been authorised by the Federal Minister of Finance to raise funds within Nigeria by the issue of £15 Million registered Stock in February. 1963. The Stocks to be issued will be:-

1. £2 Million 5 /o Federation of Nigeria Fourth Development Stock 1968 to be repaid in full on 5th August, 1968.
2. £3 Million 51/4o/oFederation of Nigeria Founrth Development Stock 1972 to be repaid in full on 5th August, 1972.
3. £10 Million 53/4o/o Federation of Nigeria Fourth Development Stock 1987 to be repaid in full on 5th August, 1987.

The three Stocks will be issued at par in multiples of £10 and applications will be accepted at banks throughout Nigeria or at the offices of the Central Bankin Lagos and Kano up to the close of business on 5th Febuary, 1663.

Prospecuses, which contain full information and application forms may be obtained from banks and Stockbrokers or at theCentral Bank's offices in Lagos and Kano up to the close of business on 5th Febuary, 9631.

W. A. TIBBLES,
GENERAL MANAGER
CENTRAL BANK OF NIGERIA.

JANUARY 1963.

## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

### INVITATION TO TENDER

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of the undermentioned scrap materials now lying on the Authority's premises. (1) at Apapat Quays (2) at Apapa Dockyard and (3) at Port Harcour Quays, –

APAPA

| Lot No | Description | |
|---|---|---|
| 1. | Morris Oxford Traveller | LD.3218 |
| 2. | ,, ,, ,, | LD.5729 |
| 3. | Morris Van 30 cwt. | LB.2372 |
| 4. | Bedford Lorry 5 ton | LB. 145 |
| 5. | Moris Lorry 5 ton | LB.4012 |
| 6. | Morris Kit Car 10 Seater | LB.2536 |
| 7. | Morris Van 10 1/2 cwt. | LB.2537 |
| 8. | Ford Consul Saloon | LC.5717 |
| 9. | 6 Electric Motors ) 2 Generators ) As one lot 4 Brake solenoids) | |
| 10 | 1 1/2 Ton Portal Crane No. 507A. | |
| 11. | 43 Lead Acid Batteries–As one lot. | |
| 12. | 22 Refrigerators ) 16 Cookers ) 8 Ceilling Fans ) As one lot 4 Table Fans ) 7 Water Heaters ) | |
| 13. | 5 Electric Rivet Heating Machines–As one lot | |
| 14. | 101/2" Centre Lathe No. 017 | |
| 15. | 8" ,, ,, No. 036 | |
| 16. | 8" ,, ,, No. 034 | |
| 17 | 138 No 44 Gallon Drums ) 71 ,, 10 Gallon Paint, Grease and Whitewash Drums ) 480 ,, 5 Gallon Paint Drums ) 214 ,, 4 Gallon Kerosene Tins )As one lot 37 Nail Drums ) 39 Carbide Drums ) 17 No. 2 Gallon Paint Tins ) 5 ,, 1 Gallon White Lead Paint Tins ) | |

PORT HARCOURT

| Lot No. | Description |
|---|---|
| 18. | One Ramsom Repier Crane No 664 |
| 19. | 7 Refrigerators – as one lot. |

2. The above items may be inspected on application to the following officers of the Authority between the hours of 8 a.m. – 12 noon and 2 p.m. – 4 p.m. not later than Wednesday 16thJanuary 1963 :–

Lots Nos. 1-12, Senior Stores Officer, Apapa Quays
Lots Nos. 13–17, Senior Stores Officer, Apapa Dockyard
Lots Nos. 18–19, Senior Stores Officers, Port Harcourt Quays,

3. A copy of the Form of Tender may be obtained fr m the Secretary, Nigerian Ports Authority, 216, Broad Street, Lagos, and from the Port Manager, Eastern Ports, Nigerian Ports Authority, Port Harcourt, on payment of £20 (Twenty pounds) to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays or Ports Harcourt Quays, as the case may be.

4. The completed Form of Tender should be returned to the Secretary, Nigerian Ports Authority, 216, Broad Street, Lagos, in a sealed envelope marked "CONFIDENTIAL – TENDER FOR SCRAP MATERIALS" as to reach him not later than 4 p.m. on Friday 25th January, 1963.

5 The successful tenderer, upon being advised of the acceptance of his tender, will be required to pay for the scrap materials within 7 days of the date of notification of such acceptance, and also t cu (where necessary) and remove the scrap materials, at his own expense within 7 days of the date of payment of the purchase price The deposit of £20 will not be refunded in any event to any tenderer who fails to pay for, and remove the materials as stipulated.

6 The Authority reserves the right to resell any materials not removed by the purchaser after 7 days of payment of the purchase price, and such purchaser shall forfeit such payment in the event of such non-removal.

7 The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

N.P.A. Notice No. 849
7th January 1963

B. A. KEHINDE,
Secretary to the Authority

# Itan Alake

Obẹrẹ loju ewe kẹta

ni nwọn bẹrẹ si yinbọn pa awọn alaiṣẹ.

Ija na pọ tobẹgẹ ti Ọba Gbadebọ paapa fi sa kuro ni Afin ti o salọ si ọdọ ọrẹ rẹ padi ti anpe ni Father Coquard ninu ile awọn Alaisan ti awọn Ijọ Ṣọsi Aguda kọ si Itẹsi Abẹokuta nigbana. Eyi fi ara pamọ fun gbogbo awọn ara ilu ti nwọn ko fi mọ ibiti o sa gba. Awọn miran ni nwọn ti bẹ ori Ọba Gbadebọ ni awọn ko ṣe rii ni ilu mọ.

# Eleti–Ọfe D'araba




## [illegible]go Promotes Contest For New African Authors

[illegible] the international [illegible] magazine devoted [illegible] the interests of all peo[ple] of Negro origin.

This monthly publication [wh]ich hope to follow its [ve]ry successful entry into [W]est Africa with special [ed]itions to cover the whole [of] Africa, has announced [a] short story contest entry [f]or which is limited to au[th]ors of African or Cari[bb]ean origin who are not [es]tablished authors.

The first prize will be [£]100 and five other prizes [o]f £20 each will be given. [T]he closing date is July [illegible] full details of the [illegible] month in [illegible]

## New Mosque For London

LONDON: A large mosque with a Minaret is to be built in London's Regent's Park on land donated by the British Government. Its estimated cost is about £1-million, of which £250,000 has already been contributed by Nigeria and 19 other predominately Moslem countries, and by personal gifts from the Aga Khan, the Nizam of Hyderabad, and President Bourguiba.

## New Prime Minister For S. Rhodesia



Sir Edgar Whitehead, who had been Prime Minister of Southern Rhodesia since 1958, has been succeeded by Mr. Winston Field following the recent elections. Sir Edgar first entered government service in 1928, but left to take up farming. Before his appointment as Prime Minister, he was Minister for the Federation of Rhodesia and Nyasaland in Washington.




**Iwọ ha nwa asiki funra rẹ bi?**

**Ki yio pẹ lọ titi fun ọ bi o ba nfi owo pamọ latigba dẽgba nile ipamọ owo ti Barclays**

Owo rẹ nbẹ labẹ abo lọwọ Barclays. Ki yio sọnu atipe bi o ti npẹ nibẹ si bẹni yio ma lési. Lọ bère nibiṣẹ Barclays tombẹ nitosi ọdọ rẹ nipa fifi owo pamọ ki o si bẹrẹ lati ṣe bẹ ni kiakia.

**"BI IWỌ BA N[illegible] ASIKI FUNRA[illegible]**

[illegible]



[illegible]



[illegible]

**BARCLA[YS] BANK D.C.O.**

**Aworan yi ni ti awon elere bolu ilu Chelsea nigbati nwon nfi aga gba'ga pelu awon elere bolu ilu Newcastle. Boya ko ni si ikuuku pupo loni ni ilu Oyinbo nwon a si le gba bolu won na loni.**




**E POLOWO OJA YIN SINU IWE IROHIN ELETI–OFE**


Advertisement No. 12

## National Sports Council Of Nigeria

VACANCY FOR ASSISTANT SECRETARY

Applications are invited from suitably qualified Nigerians for the post of Assistant Secretary to the National Sports Council of Nigeria. The General Conditions of Service for the successful candidate will be similar to those observed in the Federal Government Service.

2. QUALIFICATIONS

A University Degree or its equivalent or considerable administrative experience with a good educational background; a practical knowledge of Nigerian sport will be an advantage. Full consideration will be given to the applicant's character, record of integrity and temperamental suitability to deal with public affairs.

3. DUTIES

The successful candidate will be responsible for office organisation and will also be required to assist the Secretary in implementing and directing all activities arising from the fulfilment of the Council's policy.

4. SALARY

The salary attached to the post will be £720 x 42–£804; £924 x 48 – £1,260; £1,314 x 54 – £1,584. Point of entry will depend on candidate's qualifications, present salary and experience.

5. METHOD OF APPLICATION

Applications, with the names of two Referees, should be sent to:–

The Acting Secretary,
National Sports Council of Nigeria,
c/o Private Mail Bag 5106,
Ibadan,

so as to reach him not later than February 8th, 1963.

Applications from candidates employed by Government or any of the Statutory Corporations must be submitted through the applicant's Head of Department and should be accompanied by a Confidential Report.



Advertisement No. 10

## National Sports Council Of Nigeria

VACANCY FOR SECRETARY

Applications are invited from qualified persons for the post of Secretary to the National Sports Council of Nigeria. The general conditions of service for the successful candidate will be similar to those observed in the Federal Goverment Service.

2. QUALIFICATIONS

A University Degree is desirable; but greater importance will be placed on administrative experience of not less than seven years and a practical knowledge of Nigerian sport. Full consideration will be given to the applicant's character, record of integrity and temperamental suitability to deal with public affairs.

3. DUTIES

The successful candidate will be required to act as the Council's Chief Executive Officer and therefore will have to implement the policy and direct all activities arising from the fulfilment of the Council's policy.

4. SALARY

The salary attached to the post will be £2,292 per annum.

5. METHOD OF APPLICATION

Applications, with the names of two Referees, should be sent to:–

The Acting Secretary,
National Sports Council of Nigeria,
c/o P. M. B. 5106,
Ibadan,

so as to reach him not later than February 8th, 1963.

Applications from candidates employed by Government or any of the Statutory Corporations must be submitted through the applicant's Head of Department and should be accompanied by a Confidential Report.